# "TANI WA NIHA TI OLUWA?"

## Ẹksodu 24:12-18; 31:18; 32:1-35

### ẸKỌ 67 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi" (Ẹksodu 20:3).**

**I A Pe Mose lọ sori Oke**

1. A sọ fun Mose pe yoo gba walaa okuta ti a fi ìka Ọlọrun kọ, Ẹksodu 24:12; 31:18
2. Mose mu Jọṣua pẹlu ara rẹ lọ si Oke Ọlọrun, Ẹksodu 24:13
3. Aarọni ati Huri ni yoo maa ṣe oluṣọ-agutan agbo nigba ti Mose kò si ni ile, Ẹksodu 24:14; Iṣe Awọn Apọsteli 20:28
4. Ogo Oluwa wà lori oke fun ọjọ mẹfa, Ẹksodu 24:16, 17
5. Mose lọ siwaju Ọlọrun, Ẹksodu 24:18

**II Ipadabọ Mose Pẹ́**

6. Suuru tan awọn eniyan naa, wọn si wi fun Aarọni pe ki o dá
7. oriṣa fun wọn ti yoo maa ṣiwaju wọn lọ, Ẹksodu 32:1
8. Aarọni ṣe ẹgbọrọ maluu wura kan, Ẹksodu 32:2-4
9. Awọn eniyan naa rú ẹbọ, Ẹksodu 32:5, 6

**III Oluwa Paṣẹ ki Mose Sọkalẹ lati ori Oke**

10. Awọn eniyan naa ti ba ara wọn jẹ, Ẹksodu 32:7, 8, 17-25
11. Mose fọ́ wala okuta meji naa, Ẹksodu 32:15, 16, 19; Deuteronomi 9:16, 17

**IV Mose Ni Ẹnu Bode**

12. Mose pe wọn nija pe, "Ẹnikẹni ti o wà ni ìha ti OLUWA," Ẹksodu 32:26; 1 Awọn Ọba 18:21
13. Awọn ọmọ Lefi jade wa, a si paṣẹ fun wọn ki wọn ki o ya ara wọn sọtọ, Ẹksodu 32:26-29
14. Oluwa fẹ pa awọn eniyan naa run ki O si fi Mose ṣe baba orilẹ-ède kan, Ẹksodu 32:10
15. Mose bẹbẹ fun wọn, Ẹksodu 32:11-13, 31, 32; Romu 9:3; Isaiah 53:12
16. "Ẹnikẹni ti o ṣẹ̀ mi, on li emi o parẹ́ kuro ninu iwé mi," Ẹksodu 32:33; Esekiẹli 18:4
17. Ikú ni ère ẹ̀ṣẹ, Ẹksodu 32:28, 34, 35; Romu 6:23

**ALAYE**

**Ofin ti a Kọ**

Ni ṣisẹ n tẹle, Oluwa mu awọn eniyan Rẹ̀ jade kuro ni Egipti, o si jẹ ki o di mimọ̀ fun awọn ara Egipti ati fun awọn eniyan Rẹ̀ pe Oun ni Ọlọrun otitọ ati Ọlọrun alaaye. O mú wọn wá si Oke Sinai ki O ba le ba wọn dá majẹmu mimọ́ kan. Wọn ti ri idajọ ti Oluwa mu wa sori awọn ara Egipti; nigba ti Oluwa si sọkalẹ sori Oke Sinai ninu awọsanma ṣíṣú dùdù, ti oke naa mì titi, ti ipe si n dún kikankikan, ti manamana kọ, awọn eniyan naa fa sẹyin, wọn si wi fun Mose pe, "Iwọ ma bá wa sọ̀rọ, awa o si gbọ́: ṣugbọn máṣe jẹ ki Ọlọrun ki o bá wa sọ̀rọ, ki awa ki o má ba kú" (Ẹksodu 20:19). Rò o wò bi yoo ti dun Ọlọrun to lati ri i pe awọn eniyan Rẹ̀ fa sẹyin (Heberu 10:38)! Ṣugbọn o tun fi aanu Rẹ̀ hàn sibẹ, O si pe Mose si ori oke lati fun un ni ofin ati ilana Rẹ̀.

Bi o tilẹ jẹ pe oke naa mì tìtì ti o si wariri, ti ina si n jó nibẹ, Mose jẹ́ ipe Ọlọrun o si lọ si aarin ikuuku naa ti Ọlọrun wà. "Iran na si lẹrù tobẽ, ti Mose wipe, ẹ̀ru bà mi gidigidi, mo si warìri" (Heberu 12:21). Mose gbẹkẹle Ọlọrun o si fi igboya gbọran si Oluwa bi o tilẹ jẹ pe ẹru bà a. Ọlọrun pa Mose mọ́, bi o tilẹ jẹ pe fun odidi ogoji ọsan ati ogoji oru ko jẹ ounjẹ, bẹẹ ni kò mu omi (Deuteronomi 9:9). Lẹyin ti Jesu ti gbaawẹ fun iye ọjọ kan naa O fi ọrọ wọnyii ṣẹgun Satani, "A ti kọwe rẹ̀ pe, Enia ki yio wà lãyè nipa akara nikan, bikoṣe nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wá" (Matteu 4:4). Mose wà lori oke lati gba Ọrọ Ọlọrun; gẹgẹ bi Jobu, o pọn ọn le "jù ofin inu" rẹ̀ lọ.

Oluwa ti sọ Ofin wọnni fun Mose ni ọrọ ẹnu, Israẹli si ti ṣeleri lati pa a mọ́; ṣugbọn Oluwa tun pe Mose pada sori oke ki o ba le fun wọn ni Ọrọ naa ni akọsilẹ. A le ri ọgbọ́n Oluwa ti O fẹ ki wọn ní Ọrọ naa ni akọsilẹ. I bá ti rọrun fun wọn lati yí Ọrọ ti a fẹnu sọ pada ṣugbọn wọn ki yoo le ṣe bẹẹ si Ọrọ ti a kọ silẹ. Oluwa maa n jowu fun Ọrọ Rẹ̀ nigba gbogbo. Orin Dafidi 138:2 sọ pe, "Iwọ gbé ọ̀rọ rẹ ga jù gbogbo orukọ rẹ lọ."

**Ofin ti a Fọ́**

O rọrun fun wa lati sọ idi rẹ̀ ti ibinu Mose fi ru to bẹẹ nigba ti o ri i pe Israẹli ti yara yi pada si ibọriṣa. O jẹ iyalẹnu fun Paulu, ni akoko ti rẹ̀, pe awọn ara Galatia tete yí pada kuro ninu oore-ọfẹ Kristi si Ihinrere miiran (Galatia 1:6). Israẹli ti ba majẹmu wọn pẹlu Ọlọrun jẹ́. Nigba ti ẹni kan ba yẹ majẹmu tabi adehun ti o ba ẹni keji rẹ̀ ṣe, ko tun si ide kan ti o de ẹni keji lati mu ipa ti rẹ̀ ṣẹ ninu adehun naa. Mose fọ́ awọn walaa okuta naa lati fi

hàn pe Ọlọrun ko tún ni mu ipa ti Rẹ̀ ṣẹ ninu Majẹmu naa. Ọlọrun ki i kuna lati mu Ọrọ Rẹ̀ ṣẹ, ṣugbọn nigba ti awọn eniyan ba kuna lati mu majẹmu wọn ṣẹ, yoo jẹ́ idiwọ fun Ọlọrun lati mu ipa ti Rẹ̀ ṣẹ.

**Awọn Oluṣọ-agutan**

A fi Aarọni ati Huri si ipo oluṣọ-agutan kekere. Dipo ki Aarọni jẹ oloootọ oluṣọ-agutan, o hu iwa òṣèlú -- o ni awọn eniyan naa n fẹ ọlọrun ti yoo maa lọ ṣiwaju wọn. Aarọni, gẹgẹ bi alagbaṣe, "ẹniti awọn agutan kì iṣe tirẹ̀" gba awọn eniyan naa laye lati tẹle ọna ti wọn. Mose ko gbọjẹ̀gẹ́ pẹlu wọn, ati gẹgẹ bi Oluṣọ-agutan tootọ, o n fẹ lati fi ẹmi rẹ̀ lelẹ nitori awọn eniyan naa. Bi Oluwa kò ba le fi ọkàn tán wa lori awọn nnkan kékèké, bawo ni Oun yoo ṣe le fi ọrọ̀ tootọ sabẹ itọju wa?

**Mose Pe Israẹli Nija**

Igboya ti Mose fi duro lẹnu bode ti o si pe gbogbo Israẹli ni ija fi iwa wolii tootọ ti o kún fun Ẹmi Ọlọrun hàn. Awọn ọlọtẹ eniyan ni o n penija -- awọn eniyan ti wọn ti fi oju ara wọn ri iṣẹ iyanu, ti o si yẹ ki wọn pinnu lati gbẹkẹle Ọlọrun. Mose dá duro gedegbe, o si kigbe pe, "Ẹnikẹni ti o wà ni iha ti OLUWA, ki o tọ̀ mi wá" (Ẹksodu 32:26).

Ẹya kekere ti Lefi jade wa. O gba igboya ninu ọkàn wọn lati le jade kuro laaarin ogunlọgọ eniyan bẹẹ, ki wọn si tọ Mose lọ ni ẹnu ibode. Bakan naa ni o gba igboya fun ẹlẹṣẹ lati le jade laaarin ọpọlọpọ eniyan ti o wà ninu ile-isin ki o si la aarin wọn kọja lọ wolẹ̀ nibi pẹpẹ adura. Onigbagbọ́ pẹlu jẹ́ onigboya eniyan. Laaarin ẹgàn ati iyọṣuti si, yoo duro fun otitọ. Oun yoo mú iduro rẹ̀ lori Ọrọ Ọlọrun bi o tilẹ jẹ pe baba tabi iya rẹ̀ da a lẹbi tabi ki wọn sọ̀rọ abuku si ọna ti o n rin. Jesu wi pe "Ẹniti o ba fẹ baba tabi iya jù mi lọ, kò yẹ ni temi" (Matteu 10:37). Awọn ẹya Lefi mu iduro wọn laaarin idojukọ awọn arakunrin wọn, awọn ẹlẹgbẹ wọn ati awọn aladugbo wọn. O gba pe ki a fi ohun ti o ṣọwọn ju lọ fun ọkàn wa lelẹ lati jẹ ọmọ-ẹyin Kristi. Ere nla ni o n wà fun awọn ti o fi igboya mu iduro wọn fun Ọlọrun.

Nigba ti awọn ẹya Lefi jade wa si iha ti Oluwa, kiakia ni ipenija Mose yí pada si ọ̀rọ ikini-laya. O gba wọn niyanju lati ya ayé wọn sọtọ fun Oluwa ki o ba le fi ibukun si wọn lori. Nigba miiran a maa n pè wá lati ya ara wa sọtọ lati ṣe ohun ti o ṣoro; ṣugbọn Ọlọrun maa n fun ni ni agbára lati jẹ ipe naa, ibukun yoo si tẹle e.

**Mose, Alagbawi**

Nigba ti Mose duro niwaju awọn eniyan naa, o ṣe gẹgẹ bi oloootọ ọmọ-ogun ati alakoso, ṣugbọn nigba ti o de iwaju Ọlọrun, o rẹ ara rẹ̀ silẹ o si doju rẹ̀ bolẹ̀, o kigbe pe "Yẽ, awọn enia wọnyi ti dá ẹ̀ṣẹ nla, nwọn si dá oriṣa wurà fun ara wọn" – o jẹwọ ohun naa ti wọn ṣe. Awọn ẹlomiran maa n gbiyanju lati wá aanu lai jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn. Ọrọ Ọlọrun ni ẹnikẹni ti o ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ba si kọ ọ silẹ yoo ri aanu. Ko tun si ẹ̀ṣẹ miiran ti Israẹli le ṣẹ ti o tobi ju yiyipada kuro lẹyin Ọlọrun alaaye si ibọriṣa. Ofin kin-in-ni sọ pe, "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi" (Ẹksodu 20:3).

Israẹli ti dẹṣẹ, ṣugbọn Mose bẹbẹ fun aanu: "Bi iwọ o ba dari ẹ̀ṣẹ wọn ji wọn --; bi bẽ si kọ, emi bẹ̀ ọ, pa mi rẹ́ kuro ninu iwé rẹ ti iwọ ti kọ" (Ẹksodu 32:32). Idahun ti Oluwa fi fesi jẹ gẹgẹ bi ẹtọ: "Ẹnikẹni ti o ṣẹ̀ mi, on li emi o parẹ́ kuro ninu iwé mi" (Ẹksodu 32:33). I bá ma ṣe pe Mose ni agbara lati gba agbayọri adura si Ọlọrun, n ṣe ni a ba pa awọn Ọmọ Israẹli run. Lẹyin naa Mose sọ fun Israẹli pe, "OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé wolĩ kan dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakunrin rẹ, bi emi" (Deuteronomi 18:15). A ní Wolii naa gẹgẹ bi Alagbawi wa lọdọ Baba lonii, ani Jesu Kristi olododo.

## AWỌN IBEERE

1. Iṣẹ́ ọwọ́ ta ni awọn walaa okuta naa i ṣe?
2. Bawo ni Mose ti pẹ́ to lori oke naa?
3. Ta ni a fi ṣe alabojutó Israẹli nigba ti Mose kò si nile?
4. Bawo ni ogo Ọlọrun ṣe fara hàn fun Israẹli?
5. Wa ẹsẹ Bibeli kan ti o sọ inu Ọlọrun nipa Aarọni ni akoko yii?
6. Ki ni awọn ọna marun-un ti Israẹli ti gba fi ba ara wọn jẹ́?
7. Ki ni Ọlọrun n fẹ ṣe si Israẹli?
8. Ki ni awọn kókó ti Mose tẹnu mọ́ ninu ẹbẹ rẹ̀ fun Israẹli?
9. Njẹ Aarọni gbà pe oun ni o jẹbi ohun ti o ṣẹlẹ yii?
10. Ta ni dahun nigba ti Mose wi pe, "Ẹnikẹni ti o wà ni ìha ti OLUWA, ki o tọ̀ mi wá?"
11. Ki ni ohun ti a ni ki wọn ṣe?
12. Ki ni ẹkọ ti ẹmi ti o ri kọ́ ninu ohun ti wọn ṣe?